# NI ỌNA EMMAUSI
## Luku 24:1-48
## ẸKỌ 65 -- FUN AGBA

**Akọsori: "Emi ni ajinde, ati ìye: ẹniti o ba gbà mi gbọ́, bi o tilẹ kú yio ye" (Johannu 11:25).**

**I Awọn Obinrin lọ si Iboji Lowurọ Kutukutu**

1 Wọn mura wa lati fi ororo kun ara Oluwa wa, Luku 24:1; Marku 16:1, 2
2 A ti yi okuta kuro – iboji si ṣofo, Luku 24:2-7; Matteu 28\:2-6; Marku 16:4-6; Johannu 20:1-8
3 A mu ihin angẹli naa tọ awọn ọmọ-ẹhin lọ gẹgẹ bi aṣẹ angẹli naa, Luku 24:8-10; Matteu 28:7, 8
4. Awọn ọô-ẹhin kò gba ọrọ awọn obinrin naa gbọ́, Luku 24:11, 12; Marku 16:9-11

**II Awọn Ọmọ-ẹhin Meji ni Ọna Emmausi**

1. Bi wọn ti jumọ n sọrọ lọ nipa kikan ti a kan Jesu mọ agbelebu, Jesu sun mọ wọṅ. O n bá wọn rin lọ, Luku 24:13-15
2. Awọn ọmọ-ẹhin naa kò mọ pe Oluwa ni, wọn sọ fun Un nipa Jesu ti a kà mọ agbelebu ati ti irohin awọn obinrin ti o lọ si iboji, Luku 14:16-24
3. Kristi tumọ̀ Iwe Mimọ́ fun awọn ọmọ-ẹhin naa bi wọn ti jumọ n lọ, Luku 24:25-27
4. Bi ilẹ ti n ṣú lọ, wọn rọ Ọ ki o ba wọṅ duro Luku 24:28, 29

**III Ifarahàn Kristi ninu Bibu Akara**

5. Oju awọn ọmọ-ẹhin naa là wọn si mọ Ẹni ti I ṣe, ki O to nù mọ́ wọn loju, Luku 24:30, 31
6. Wọn pada si Jerusalemu loju kan naa, wọn si lọ sọ fun awọn ọmọ-ẹhin, Luku 24:32-35; Marku 15:12, 13
7. Kristi ara hàn larin ipejọpọ awọn ọmọ-ẹhin Rẹ̀, O fi ọwọ́ ati ẹsẹ Rẹ̀ hàn wọn, O ṣI won niye kuro ninu okú, Luku 24:36-48; Sekariah 13:1; I Timoteu 1:5; I Peteru 1:18, 19; Heberu 9:22

## ALAYE

**Awọn Obinrin lọ si Iboji ni Kutukutu Owurọ.**

Ni ọjọ kinni ọsẹ ni kutukutu owurọ, awọn obinrin ti wọn ti n tẹle Jesu lati Galili (Luku 23:55) pada lọ si iboji nibi ti a gbé tẹ Ẹ si. Ọjọ yi jẹ ọjọ kan naa pẹlu ọjọ ọsẹ̀ ti wa, o si jẹ ọjọ ti o tẹle ọjọ Isinmi ti awọn Ju. Wọn ti duro lati igba ti a ti sin Jesu Karisti ni ọjọ kẹfa Osẹ titi di owurọ ọjọ yi, nitori a ti paṣẹ ninu Ofin pe wọn gbọdọ sinmi ni ọjọ Isinmi Luku 23:56). Dajudaju, bi wọn ti n lọ, ọkan wọn bajẹ nitori wọn nireti ati ri okú Oluwa wọn ti wọn fẹ fi turari kún, ninu iboji Josẹfu. Nitori naa wọn mú ororo ikunra lọwọ, iru eyi ti wọn maa n lò fun okú nigba ti wọn bá fẹ sin in. Josẹfun ara Arimatea ati Nikodemu ti ara Oluwa wa silẹ fun isinkú nigba ti a tẹ Ẹ sinu iboji (Johannu 19:39, 40); sibẹsibẹ; pẹlu ikanju ati aifara balẹ ni wọn fi yara ṣe eto yi nitori ọjọ Isinmi ti wọle tàn.

Iyanu nla ni o jẹ fun awọn obinrin yi, nigba ti wọn ri I pe a ti yi okuta kuro lẹnu iboji naa; o tun ya wọn lẹnu ju bẹẹ lọ, nigba ti wọn wọ̀ inu rẹ̀ ti wọn si ri I pe a ti gbé oku Jesu lọ. Ṣugbọn laarin idaamu wọn awọn ọkunrin meji alaṣọ didan duro lẹba ọdọ wọn, wọn si jiṣẹ iyebiye ni ti o ti gbà gbogbo aye kan lati (nkan bi ọgọrun ọdun mọkandilogun) igbà naa wá pe: Eṣe ti ẹnyin fi nwá alãye lãrin awọṅ okú/ Kò si nihinyi, ṣugbọn o jinde" (luku 24:5, 6). A kò le sọ tán, ire ti ọrọ wọnyi ṣe fun awọn wọnyi ti wọn fẹran Jesu tọkantọkan.

**Ọmọ-ẹhin Meji Lọna Emmaeusi**

Lati Jerusalẹmu si Emmausi jẹ ibusọ meje aabọ, boya o si gba awọn ọmọ-ẹhin meji yi, ti ọkan ninu wọn n jẹ Kleopa, tò wakati meji lati debẹ. Bi wọn ti n lọ, wọn n sọrọ nipa ohun gbogbo ti o ti ṣẹlẹ, boya nipa Ase-ale ikẹhin ati idajọ erú ati iku oró Jesu. Boya wọn tilẹ jiroro lori ọrọ ti Jesu ti ba wọn sọ, nigba ti O sọ fun wọn nipa ikú ati ajinde Rẹ̀ ti yoo ṣẹlẹ ni ọjọ iwaju. Jesu dara pọ̀ mọ́ wọṅ loju ọna naa, ṣugbọn Oun fi ara Rẹ̀ pamọ́, O si bẹrẹ si ba wọn sọ̀rọ.

Jesu beere pe, Ọ̀rọ kili ẹnyin mba ara nyin sọ bi ẹnyin ti nrin, ti ẹ si fajuro?" (Luku 24:17); dajudaju ibeere yi wa ki wọn ba le ṣI ọkan wọn paya, ki wọn si sọ gbogbo ẹdun wọn fun Jesu. O fara hà bi aleji si wọn nigba naa, ṣugbọn O fi ifẹ han ninu ipo ibanujẹ wọn. Eyi yẹ ki o mu wọn fẹ ẹ mọ̀ ẹni ti olubeere yi I ṣe, Ṣugbọ a rú wọn li oju ki nwọn ki o má ṣe le mọ̀ ọ;" wọn kò si mọ̀ pe aleji yi ni Oluwa ati Olukọni wọn ti O jinde.

Dafidi ti le ni iru iriri yi, nigba ti o kọwe bayi. Nitori iwọ ni imọlẹ mi,OLUWA: Oluwa yio si sọ okunkun mi di imọlẹ" (II Samuẹli 22:29). Ọlọrun kò jẹ kọ awọn ti o fẹ Ẹ silẹ. Awọn meji wọnyi tú ẹdun ọkan wọn jade. Jesu si fi tẹ̀duntẹdun ati ifara balẹ gbọ́ ti wọn. Wọn yé Ọmọ Ọlọrun si nigba ti wọn wi pe Jesu ti Nasarẹti yi, ẹni ti iṣe woli, ti o pọ̀ ni iṣe ati li ọ̀rọ niwaju Ọlọrun ati gbogbo enia." Ṣugbọn a le sọ wi pe wọn kò ni oye kikún pe Oun ju woli lasan lọ, ati pe Ọmọ-Ọlọrun ni Jesu I ṣe -- Ọrọ Ọlọrun ti o di Ara.

Boya igbagbọ awọn ọkunrin yi ti n mi nitori awọn nkan ibanujo ti ṣẹlẹ ni ọÒ diẹ sẹhin; nitori Kleopa wi pe "Bẽni on li awa ti ni ireti pe, on ni iba da Israẹli ni ide" (Luku 24:21). Ọrọ wọn dabi ẹni pe wọn kò tún gbagbọ́ mọ pe Jesu ni Oludande Israẹli. Ṣugbọn Oluwa tún mu ki o dá wọn loju ni ti awọn asọtẹlẹ ti a ti sọ nipa OUn tikara Rẹ̀, ọkan sọ si gboná nipa ọ́rọ oore-ọfẹ Tẹ̀; nitori pe nigba ti oju wọn là, wọn wi pe Ọkan wa kò ha gbina ninu wa, nigbati o mba wa sọ̀rọ li ọna, ati nigbati o tunmọ̀ Iwe Mimọ fun wa?"

Ọrọ yi, **"ẹnyin ti oye ko ye"** ti a lo ni Luku 24:25, le ye ni bi ẹni pe Oluwa wi pe **alaigbọn tabi awọn ọmọde**, ti o si yatọ̀ si bi a ti n lò o ninu ede OYINBO LODE ONI. Jesu sọ fun wọn ni pataki nipa awọnasọtẹlẹ nipa Rẹ̀ ti o wá ninu Majẹmu Laelae nitori eyi ni gbogbo bibeli ti wọn ni igbaa naa. Ohun ti o tobi ti a tẹmọ́ ninu Majẹmu laelae ni bibọ̀ Messia ati èto igbala nla Rẹ̀, o si yẹ ki ohun gbogbo ti o ti ṣẹlẹ ye wọn ju bẹẹ lọ.

**Kristi Fara Han ninu Bibu Akara**

Nigba ti Jesu joko lati ba awọn ọmọ-ẹhin meji naa jẹun, O mu akara, o sure si I, o si bu u, o si fifun wọn." Eyi ni ipo oluwa ati baba laarin ẹbi, o si jẹ ọnà ti Jesu gba n fi bá awọn ọmọ-ẹhin Rẹ̀ jẹun tẹlẹ, o kere tan lẹẹkan nibi Ase-alẹ Oluwa. Awọn ọmọ-ẹhin meji yi ti le mọ̀ nipa alẹ ọjọ naa ki a to fi Jesu hàn, ati ibukun ti wọn ri gba nibẹ, nitori ni Emmausi loju kan naa ti oju wọn la ni wọn mọ̀ alejo Olubukun naa. Nigba naa ni o ù mọ wọn loju.

Lẹsẹ kan naa ni alẹ ọjọ yi (ẹsẹ 29) wọn pada si Jerusalẹmu lati rohin ayọ̀ ti ifarahan Jesu fun awọn ọmọ-ẹhin rRẹ̀ ti o pejọ sibẹ. Bi wọǹ si ti bẹrẹ si I sọ fun awọǹ ti o ti bẹrẹ si pejo pọ̀ ni ọjọ kinni ọsẹ, Oluwa duro laarin wọn, nipa bayi, O fi ọwọ̀ si ijosin ti ọjọ titun naa ti wọn dá silẹ. Ipejọ pọ ti ọjọ kinni yi, ni o pada di iranti ọjọ ajinde Kristi.

Ofin Majẹmu Laelae, Majẹmu laelae ni a ti mú ṣẹ ninu Kristi ti Kristi si ti mú ṣẹ pẹlu. Aṣọ ikele Tẹmpili ti faya nigba ti O kú, eyi ti o fi han pe gbogbo wa le wọ Ibi Mimọ́ ju lọ ti ẹmi nisinsinyi, ki a si gbà ibukun wọnni ti awọn eniyan mimọ́ ti Majẹmu Laelae kò ri gbà. A kò ṣá awọn ododo èt iṣẹ isin wọn. Ẹlẹṣẹ ti o ronupiwada kò tun ni lọ si ibi kpataki kan, tabi si ile pataki kan ti a fi ọwọ́ eniyan kọ́, lati ba Ọlọrun sọ̀rọ (Johannu 4:21-14); nitori olusin tootọ́ ni ẹmi ti n sin Baba ni ẹmi ati ni otitọ́.

Awọn Onigbagbọ́ kò sin ni ọjọ Isinmi awọn Ju mọ́, eyi ti awọn olukọni ẹ̀kọ́ èké tẹnu mọ́ pe a fi lelẹ bi iranti igbà didá aye. Awọn Apọsteli ati awọn ọmọ-ẹhin maa n lọ sinu sinagogu ni ọjọ isinmi awọn Ju, ki wọn ba le ri àyè ba awọn Ju ti wọn pejọ sibẹ sọrọ nipa Jesu ati agbara Tẹ̀ ti o le gbalà (Iṣe Awọn Apọsteli 14:1). Ṣugbọn ọjọ kinni ọsẹ ti di ọjọ ijọsin wọn, wọn si pa a mọ́, gẹgẹ bi a ti n ṣe loni ni iranti Ẹdá Titun labẹ́ igbà oore-ọfẹ -- ti I ṣe aṣepe etò irapada wa nigba ti Jesu jinde kuro ninu okú, ti O si fi agbara Rẹ̀ hàn lori iku ati Eṣu.

Ifarahà Jesu lai rò tẹlẹ mu ẹru ati iyanu bá awọn ọmọ-ẹhin lakọ́kọ́. Ṣugbọn Jesu tù wọn ninu, O si le iyemeji ati ẹ̀ru wọn lọ, bi O ti n fi ye wọn ohun wọnni ti Iwe mimọ́ wi nipa Oun tikara Rẹ̀, O la a ye wọn pe gbogbo eyi ṣẹ "ki a wasu ironupiwada ati idariji ẹ̀ṣẹ li orukọ rẹ̀ li orilẹ-ede gbogbo" (Luku 24:47).

**AWỌN IBEERE**

1. Eeṣe ti awọn obinrin naa fi lọ si iboji ni kutukutu owurọ?
2. Kin ni awọn angẹli naa sọ fun awọn ti wọn n wa oku Jesu?
3. Darukọ awọn meta ti wọn mú ihin naa lọ fun awọn ọmọ-ẹhin.
4. Bawo ni wọn ṣe gbà irohin naa?
5. Kin ni ohun ti awọn ọmọ-ẹhin meji naa n sọ lọ ninu irin-ajo wọn si Emmausi?
6. Njẹ wọn mọ́ pe Jesu ni?
7. Kin ni Jesu ṣe lati fi nkan wọnyi ye wọn?
8. Nigba wo ni Oluwa fi ara Rẹ̀ han fun wọn, kin ni awọn ọmọ-ẹhin meji naa ṣe lẹsẹ kan naa?
9. Njẹ Iyemeji ati ẹ̀ru tun wà sibẹ nigba ti Jesu tun fara hà lẹẹkeji?
10. Kin ni ohun ti Jesu sọ nipa awọn nkan wọnni ti a kọ silẹ nipa Rẹ̀ lati ọwọ́ Mose, awọn woli ati ninu Orin Dafidi?